EFF'S SURVEILLANCE SELF-DEFENSE

# DÍDÁÀÀBÒ ARAÀ RẸ LÓRÍ ẸRỌ-ALÁTAGBÀ

https://ssd.eff.org/en/about-surveillance-self-defense

LOCALIZATION LAB

## Dídáààbò Araà rẹ lórí Ẹ̀rọ-alátagbà

Ẹ̀rọ-alátagbà jẹ́ ọ̀kan lára ìbùdó-ìtàkùn lórí ẹ̀rọ-ayélujára. Facebook ní bílíọ̀nù èèyàn tó ń lò ó, àti Instagram àti Twitter ní ẹgbẹẹgbẹ̀rún mílíọ̀nù èèyàn tó ń lò ó. A gbé ẹ̀rọ-alátagbà kalẹ̀ fún pínpín àyọkà, àwòrán àti ìwífún nípa ara ẹni. Ní báyìí ó ti di ibi-ìpéjọ fún ìkójọ àti ọ̀rọ̀.

Báyìí, ìbéèrè wọ̀nyí ṣe kókó bí a bá ń lo ẹ̀rọ-alátagbà: Báwo ni mo ṣe lè lo ẹ̀rọ-alátagbà wọ̀nyí nípasẹ̀ bẹ́ẹ̀ dáàbò araà mi? Ibi-ìkọ̀kọ̀ mi? Ìdánimọ̀ọ mi? Ọ̀rẹ́ àti alábàáṣe? Ìwífún wo ni kí n tọ́jú pamọ́ àti pé ta ni kí n tọ́júu rẹ̀ pamọ́ fún?

Ó dá lórí ohun ṣíṣe, ó lè nílò láti dáàbòbo araà rẹ láti de ẹ̀rọ-alátagbà fúnra rẹ̀, òǹlò mìíràn lórí ibùdó náà, tàbí méjèèjì

## Olobó ohun tí ó yẹ kí o kíyèsí bí o bá ń ṣí ìṣàmúlò

Ǹjẹ́ ìwọ́ fẹ́ lo orúkọ àbísọ rẹ? Ibùdó ẹ̀rọ-alátagbà mìíràn ní "ìlànà orúkọ tòótọ́," ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́. Bí o bá fẹ́ lo orúkọ àbísọ nígbàtí o bá ń forúkọ-sílẹ̀ lórí ẹ̀rọ-alátagbà, máà ṣe bẹ́ẹ̀.

- Bí o bá forúkọsílẹ̀, máà fi ìwífún rẹpẹtẹ ju bí ó ṣe yẹ lọ sílẹ̀.Bí o bá ní àníyàn láti fi ìdánimọ̀ọ rẹ pamọ́, kí o lo àdírẹ́ẹ̀sì ímeèlì àti kí o kọ̀ láti fi ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ọ rẹ sílẹ̀. Ìwífún méjèèjì wọ̀nyí tó fún ìdánimọ̀ olúkúlùkù àti pé ó ṣe é so ìṣàmúlò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ pọ̀.

- Ṣọ́ra bí o bá ń yan àwòrán ìdánimọ̀. Pẹ̀lú àfikúnun mẹ́tádatà tí ó ní ìgbà, àkókò àti ibi tí a ti ya àwòrán náà, àwòrán t'òhuntìkararẹ̀ lè sọ ìwífún mìíràn. Kí o tó ó mú àwòrán, ṣe ìbéèrè: ìta ilé ni a ti yà á ni tàbí ibi-iṣẹ́? Àdírẹ́ẹ̀sì tàbí atọ́ka òpópónà hàn nínúu rẹ̀?

- Kíyèsíi àdírẹ́ẹ̀sì IP rẹ lè ti wà lákọsílẹ̀ lásìkò ìforúkọsílẹ̀.

- Yan ọ̀rọ̀-ìfiwọlé tó lágbára àti, b'ó bá ṣe é ṣe, lo ìfẹ̀rílàdí-ọlọ́nàméjì.

- Kíyèsára fún ìbéèrè ìgbà-padà ọ̀rọ̀-ìfiwọlé gẹ́gẹ́ bíi "Ìlú wo ni a ti bí ọ?" tàbí "kí ni orúkọ ẹranko-àyànfẹ́ẹ̀ rẹ?" nítorí ìdáhùn lè jẹyọ láti inú àkọsílẹ̀ lórí ẹ̀rọ-alátagbàa rẹ. Ó lè hùn ọ́ kí o yan ìbéèrè ìgbà-padà ìṣàmúlò tí kì í ṣe òótọ́. Ọ̀nà kan tí a lè fi rántí ìdáhùn sí ìbéèrè ìgbà-padà ìṣàmúlò, bí o bá yàn láti lo ìdáhùn tí ò jẹ́ òótọ́ fún àfikún ààbò, kọ ìdáhùn sí ìbéèrè pamọ́ sínúu alábòójútó ọ̀rọ̀-ìfiwọlé.

## Yẹ Òfin Ìlànà Ibi-ìkọ̀kọ̀ Ẹ̀rọ-alátagbà wò

Ìwífún tí ẹnìkẹta kó pamọ́ jẹ́ fún lílòo rẹ àti pé ó lè lò ó fún ti òwò tàbí kí o pín-in fún ilé-iṣẹ́ mìíràn, bíi ilé-iṣẹ́ ìpòlówó ọjà. Níwọ̀n bí kíka ìlànà ibi-ìkọ̀kọ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ò fi bẹ́ẹ̀ ṣe é ṣe, ó lè fẹ́ ka abala tí ó ṣàlàyé bí a ó ṣe lo àkọsílẹ̀ rẹ, ìgbà tí a pín-in fún ẹlòmíràn, àti bí iṣẹ́ náà ṣe dáhun sí ìbéèrè agbófinró.

Ǹjẹ́ ìwọ́ fẹ́ lo orúkọ àbísọ rẹ? Ibùdó ẹ̀rọ-alátagbà mìíràn ní "ìlànà orúkọ tòótọ́," ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́. Bí o bá fẹ́ lo orúkọ àbísọ nígbàtí o bá ń forúkọ-sílẹ̀ lórí ẹ̀rọ-alátagbà, máà ṣe bẹ́ẹ̀.

Èrè-jíjẹ fún okòwò ni ẹ̀rọ-alátagbà jẹ́ àti pé ó máa ń gba ìwífún bònkẹ́lẹ́ ju ohun tí a fi sílẹ̀ lọ - ibi tí o wà, ohun tí ó kan 'ni àti ìpolówó tí a fèsì fún, ibùdó tí o ti wọ̀ rí (fún àpẹẹrẹ nípasẹ̀ títẹ "Fẹ́ràn"). Gbèròo dídígàgà kúkíìsì ẹnìkẹta àti lílo ìtànká alépa-adígàgá asàwáríkiri fún àrídájú wípé ìwífún tí ò wúlò ò bọ́ s'ọ́wọ́ ẹnìkẹta.

## Àtúnṣe Ìṣètò Ibi-ìkọ̀kọ̀ Rẹ

Nípa ti bẹ́ẹ̀, ṣàtúnṣe sí ààtòàbáwá tí a ti ṣe sílẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, o fẹ́ pín àtẹ̀jáde sígboro fún gbogbo ènìyàn, tàbí fún ẹgbẹ́ kan? Àwọn èèyàn á ṣàwárí̀ rẹ bí wọ́n bá lo ímaalì tàbí ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ rẹ? Ǹjẹ́ o fẹ́ kí ibi tí o wà jẹ́ pínpínká fúnra rẹ̀?

Bótilẹ̀jẹ́pé ẹ̀rọ-alátagbà ni ìṣètò tìrẹ, o lè rí àwòṣe.

Ìṣètò Ibi-ìkọ̀kọ̀ ń bẹ láti dáhùn ìbéèrè: "ta ló lè rí ọ?" Níbí lo ti ṣe é ṣe kí o rí ààtò tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ààtòàbáwá ("gbogboògbò," "ọ̀rẹ́ ọ̀rẹ́," "ọ̀rẹ́ nìkan," abbl), ibi tí o wà, àwòrán, bí a ṣe lè kàn sí 'ni, ìsomọ́, àti bí àwọn ènìyàn ṣe lè ṣàwárí̀ rẹ bí wọ́n bá ń ṣe ìṣàwárí.

- ààtò ìdáààbòbò (tí a ń pè ní "ààbò") níṣẹ́ púpọ̀ láti ṣe pẹ̀lú ìdígàgá/ìpohùnmọ́ ìṣàmúlò mìíràn lẹ́nu, àti bí o ṣe fẹ́ máa gba ìfihàn bí ẹni tí ó láṣẹ láti fàṣẹ fún ìṣàmúlò rẹ bá fẹ́ pàṣẹ fún un.

Ìgbà míìn, o 'óò rí ààtò ìwọlé - bíi ìfèrílàdí-ọlọ́nàméjì àti àkópamọ́ ímeèlì/ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ - nínú abala yìí. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ààtò ìwọlé wọ̀nyí yóò wà nínú ààtò ìṣàmúlò tàbí abala ààtò ìwọlé, pẹ̀lú ìyàn ìyípadà ọ̀rọ̀-ìfiwọlé.

Jẹ ànfàání “àyẹ̀wò” ìdáààbòbò àti ibi-ìkọ̀kọ̀.
Facebook, Google, àti ibùdó-ìtàkùn mìíràn bẹ́ẹ̀ ní àfifún àyẹ̀wò ìdáààbòbò. Ẹ̀kọ́ amọ̀nà wọ̀nyí á fi ibi-ìkọ̀kọ̀ àti ààtò ìdáààbòbò tí ó wọ́pọ̀ nínú èdè geere àti pé ó jẹ́ ìwò-ojú tí ó dára jù fún òǹlò.

Níparí, ṣèrántí wípé ibi-ìkọ̀kọ̀ lè yí padà. Nígbà mìíràn, ààtò ibi-ìkọ̀kọ̀ ń l'ágbára sí i, ó sì wà ní èérún; kò rí bẹ́ẹ̀ nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀wẹ̀. Se àkíyèsí àwọn àyípadà wọ̀nyí fínnífínní láti rí i bóyá ìwífún tí ó ti wà ní ibi-ìkọ̀kọ̀ rí yóò di pínpín, tàbí bí àfikún ààtò yóò fún ọ láàyè láti ṣe àkóso ibi-ìkọ̀kọ̀ rẹ.

## Tọ́jú Ìdánimọ̀ ìṣàmúlò lọ́tọ̀ọ̀tọ̀

Fún ọ̀pọ̀ ènìyàn, ó pọn dandan láti ya ìṣàmúlò s'ọ́tọ̀ọ̀tọ̀. Èyí ní í ṣe pẹ̀lú ibùdó-ìtàkùn fún ẹni-tó-ń-wá-ọkọ-wá-aya, ìṣàmúlò onímọ̀, ìṣàmúlò àìlórúkọ, àti ìṣàmúlò ní onírúurú ìlú orí ayélujára.

Ilà ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ àti àwòrán jẹ́ méjì ń'nú ìwífún tí ó yẹ kí a fojú sí. Àwòrán, ní pàtàkì, lè yọ́ mínrín so ìṣàmúlò tí o fẹ́ jẹ́ ó dá wà pọ̀. Èyí wọ́pọ̀ ní ibùdó ẹni-tó-ń-wá-ọkọ-wá-aya àti àkáùntì onímọ̀. Bí o bá fẹ́ fi ojú pamọ́ tàbí tọ́jú ìṣàmúlò kan pamọ́ fún òmíràn, lo àwòrán tí o kò lò rí níbòmìíràn lórí ayélujára. Fún àyẹ̀wò, o lè lo aṣàwárí ìyípadà àwòrán-an Google. Alásopọ̀ mìíràn tó lágbára tí ó yẹ kí a f'ojú sílẹ̀ fún ni orúkọ̀ọ̀ rẹ (pàápàá orúkọ ìnagijẹ) àti ímeèlì rẹ. Bí o bá ṣàkíyèsí wípé ọ̀kan nínú ìwífún-ùn rẹ ń bẹ níbi tí o kò lérò, máà fòyà. Dípò ìfòyà, ronú bí i ọmọ-ìkókó: kàkà kí o pa gbogbo ìwífún-ùn rẹ rẹ́ lórí ayélujára, kàn f'ojú sí ìwífún kéékèèké kan, ibi tí wọ́n wà, àti ohun tí o lè ṣe nípa wọn.

## Mọ àpadé-àti-àludé Ààtò Ẹgbẹ́ oríi Facebook

Ẹgbẹ́ oríi Facebook ń mú ibi ìkẹ́gbẹ́, ìgbàwí àti àwọn ohun tí ó lágbára àti ààtò ẹgbẹ́ lè rí rúdurùdu. Kọ́ ìmọ̀ kún ìmọ̀ nípa ààtò ẹgbẹ́ àti bóyá akópa nífẹ̀ẹ́ sí kíkọ́ ìmọ̀ kún ìmọ̀ nípa ààtò ẹgbẹ́, ṣiṣẹ́ pẹ̀lúu wọn láti mú kí ẹgbẹ́ Facebook jẹ́ ohun ìkọ̀kọ̀ àti ààbò

## Eré-ìdárayá alájùmọ̀ṣe ni ibi-ìkọ̀kọ̀

Máà kàn ṣáà yí ààtò àti ìhùwàsí ẹ̀rọ-alátagbàa rẹ padà. Tẹ̀síwájú kí o sọ fún àwọn ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ, aburú tó ń bẹ nínú kí a máa gbé nípa ara ẹni sórí ayélujára.
Kódà bí o kò bá ní ìṣàmúlò ẹ̀rọ-alátagbà, tàbí bí o bá yọ araà rẹ ń'nú táàgì tí a fi kó ọ pọ̀ mọ́ àtẹ̀jáde, ọ̀rẹ́ ṣì lè ṣèṣì dá ọ mọ̀, jẹ́ kí ibi tí o wà di mímọ̀, kí ìsomọ́ọ̀ rẹ pẹ̀lú wọn ó jẹ́ ojútáyé. Kì í ṣe dídáààbò ibi-ìkọ̀kọ̀ nìkan ni ìtọ́jú ara ẹni, àmọ́ títọ́júu àwa-ara-wa.

Àtúnṣe ìkẹ́hìn:
7-2-2018

O nílò ohun-ìmọ̀ ìdáààbò àkọ́bẹ̀rẹ̀?

Yan irinṣẹ́ẹ̀ rẹ
Dídáààbò araà rẹ lóríi ẹ̀rọ-alátagbà
Dídíyelé ewuù rẹ
Jùmọ̀ pẹ̀lú àwọn elòmíràn
Ṣe páswọọ̀dù t'ó lágbáre.
Fífi ìwífún-ùn rẹ pamọ́
Kí ni Encryption?